**Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School**

**Ose Kejidinlogun: Osu Kerin Ogbon Ojo, 2017**

**Akori Oro: Nibo ni o to isura re jo si?** – Apa Kini

**Eko Kika: Matteu 6: 19-24**

## Afihan

Isura je ohunkohun ti enia ba ntoju, ti o si nsike. Isura ni awon ohun daradara ti o niye lori ati awon ohun iyebiye ti a nfi pamo ni ibi abo.

Nigbakugba ti enia ba menuba isura, ohun ti o ma nkoko wasi okan awa enia ni owo, awon ohun oso, awon ohun alumoni, ola ati oro. Isura kan wa ti awa enia ma nfi oju fo, ti a ko si kasi. Isura pataki kan wa ti ise isura gbogbo-gbo ti Olorun Olodumare ninu akainiye anu re fi fun awa eda-enia; eyi ni emi wa tabi okan wa ti o muwa wa laaye.

Nitorina, gbogbo alaaye okan ti o ni emi-iye ni o gbodo fi emi-imore han si Oluwa Olorun fun isura ti a ko le fowora yi. " Oluwa Olorun si fi erupe ile mo enia; o si mi emi iye si iho imu re; enia si di alaaye okan" **Genesisi 2: 7**.

Idi ti a fi fun wa ni isura gbogbo-gbo yi ni lati fi polongo ise Olorun, ki a si mu igbega ba ise re ni ile alaaye. Nitorina, ojuse re ni lati lo isura ti Olorun fifun o yi ni ona ti o to, ti o si ye fun igbeleke ogo Oluwa Olorun re. Enikeni ti o ba lo isura yi fun itesiwaju ise Oluwa, yio ri awon isura miran gba lati odo Oluwa, amo enikeni ti o ba si isura yi lo, yi kabamo lori iwa buburu re. Fun idi eyi, to isura re jo sinu ijoba Olorun ati ogba-ajara re.

Bi emi re ba niye lori ti o si se iyebiye si o, iwo yio gba ohun Oluwa gbo, beni iwo yio si pa majemu re mo; nigbana li iwo yio je isura fun Oluwa ju gbogbo enia lo: nitori gbogbo aiye ni ti Oluwa **Eksodu 19: 5**.

Nitorina, mase pada sehin kuro ninu ofin enu Oluwa, ki o si pa oro enu re mo ju ohunkohun ninu aiye lo **Jobu 23: 12**. Ma yo si oro re nigbagbogbo, bi eniti o ri ikogun pupo **Orin Dafidi 119: 162**. Nigbana ni awon enia yio mo wipe, enia mimo ni iwo fun Oluwa Olorun re, Oluwa si ti yan o lati ma se enia oto fun ara re; ju gbogbo orile-ede lo ti mbe lori ile **Deuteronomi 14: 2, 7: 6**. Araiye yio wa ri daju wipe Oluwa ti yan awon kristiani fun ara re; ati awon onigbagbo fun isura aayo re **Orin Dafidi 135: 4**.

## Orisi awon isura

Awon kristiani ni lati mo wipe orisi isura meji ni o wa, ti oruko won si nje isura ti ara ati isura ti emi.

**Isura ti ara:** Awon isura ti ara ni oro, ola, owo, awon ohun oso, awon ohun alumoni ati be be lo. Bibeli wipe awon amoye meta foribale fun Kristi nwon si sin. Nigbati nwon si tu isura won, nwon ta a lore wura ati turari ati ojia **Mattheu 2: 11**. Lotito ni a ta Jesu Kristi lore pelu awon isura ti ara, sugbon awon isura yi si ni itumo nipa ti emi:

- Wura tumo si wipe Oba ni Jesu
- Turari tumo si wipe eni mimo ni Jesu
- Ojia tumo si wipe alufa ni Jesu.

**Isura ti emi:** Awon isura ti emi ni okan mimo ati eri-okan rere, pelu awon ebun Oluwa, pataki-julo emi re ti o fi fun wa. Jesu Kristi menuba eyi nigbati o mba awon Farisi wi. O wipe ninu opolopo ohun inu li enu iso, nitoripe enia rere lati inu isura rere okan re ni imu ohun rere jade wa: ati enia buburu lati inu isura buburu ni imu ohun buburu jade wa **Matteu 12: 34-35**. O ti han daju wipe inu-okan ni a ma nfi isura ti emi pamo si. Nitorina, jeki iberu Olorun je isura re, nitoripe iberu Olorun ni kokoro ti o nsi ilekun ile-isura Olorun. A kowe re wipe “ogbon ati imo ni yio je idurosinsin akoko re ati isura

igbala, iberu Oluwa ni yio je isura re" **Isaiah 33: 6**. Beru Oluwa ki o ba le ni kokoro ti isi ilekun isura-ailopin Oluwa.

## **Olorun ni o ni isura**

Awa enia ni lati moye wipe ti Olorun Olodumare ni isura. Iwe mimo wipe oro ati ola mbe lowo Oluwa, ani oro daradara ti o npe titi ati ododo ti Oluwa ni. Oluwa si nfi fun enikeni ti o ba nse ife re **Owe 8: 18**. Bi o ba nfe ola ati ibukun ati idurosinsin ninu aiye re, diromo Oluwa.

**Oro ati ola wa lati odo Olorun:** Oro pelu ati ola nwa lati odo Olorun nikan, nitoripe Oluwa joba lori ohun gbogbo: li owo re ni agbara ati ipa wa; ati li owo re ni siso ni di nla wa, ati fifi agbara fun ohun gbogbo **1 Kronika 29: 12**. Oluwa nikan ni o le fun o ni agbara, ki o si so o di eni-nla ni akoko iwa-laaye re; nitorina mase wa isura lo si ibomiran tabi ona ajoji.

**Oluwa ni nmu ise ati oro wa:** Olorun nikan ni o le mu ise ati oro wa. On nikan ni o le ran ise ati oro ni'se. O ni agbara lati reni sile ati lati soni di nla. Nigbakugba ti o ba re o sile, lati dan igbagbo re wo, eyi ko tumo si wipe koni so o di eni nla; niwon igbati o bati di igbagbo re mu sinsin ni aiseye-meji. Iwe mimo wipe "Oluwa so di talaka, o si so di oloro: o re sile, o si gbe soke". **1 Samueli 2: 7**. Opolopo enia ninu aiye loni ni won nse akitiyan ati laala ti won si nko isura jo, opo enia nko isura jo si oniruru oorile-ede ni agbaiye.

Ogoro enia ni nwon nlo isura won lati je omo enikeji ni iya ati lati fi ni awon enia lara. Akainiye enia ni nwon nhun si awon isura won lo ni orisirisi ona, eyiti nwon ko ba lo lati fi mu itesiwaju ba ise Oluwa. Iru awon enia wonyi ni oro Bibeli yi bawi "Eniti Olorun fi oro, ola ati ola fun, ti ko si si nkan ti o si ku fun okan re ninu ohun gbogbo ti o fe, sugbon ti Olorun ko fun u li agbara ati je ninu re, sugbon awon ajeji

enia li o nje e: asan li eyi, arun buburu si ni **Oniwasu 6: 2**. Lotito, Olorun fun iru awon enia yi ni oro nla ati ola, pelu ohun gbogbo ti okan nwon nfe; sugbon ko fun nwon ni anfani lati je ninu awon eso laala nwon, nitoriti nwon ko lo isura won fun Oluwa ati ise re. Awon ajoji ni won si nkore laala awon irufe enia wonyi.

Olorun ninu ailopin anu re, yio fun gbogbo okan ti o ba lo isura won gegebi igbekale ilana Olorun, ni ebun lati je ninu awon eso laala nwon **Oniwasu 5: 19**. Bi o ko ba fe ki ajoji jere ise re, ki nwon si je awon eso laala re, bi o ba nfe emi gigun lati gbadun awon eso laala re, ninu ayo, alafia ati ilera; lo awon isura re ni ona daradara.

**Oba Solomoni:** Olorun fi ara han Solomoni ni oju ala, Olorun si wipe, "bere ohun ti emi o fi fun o?" Solomoni bere fun awon isura ti emi, eyi si te Olorun lorun. Olorun fun u ni ogbon, imo ati oye; pelu awon isura ti ara, ti ise oro ati ola, ni eyiti Solomoni ko bere e fun lati odo Oluwa **1 Awon oba 3: 5-13**. Olorun wa fi igbese kan ti ire yi ni idi, wipe "Bi iwo Solomoni o ba si rin ni ona mi lati pa ase ati ofin mi mo, gege bi Dafidi baba re ti rin, emi o si sun ojo re siwaju" **1 Awon oba 3: 14**. Ife ti Solomoni ni si opo obinrin ajoji ni o fa isubu re. Nigbati Solomoni di arugbo, awon obinrin re yi li okan pada si olorun miran: okan re ko si se dede pelu Oluwa Olorun re, gege bi okan Dafidi baba re **1 Awon oba 11: 1-4**. Solomoni si nfi isura ti o yeki o ma lo fun ilosiwaju ise Olorun alaaye sike awon olorun ajoji, nitorina, Oluwa fa ijoba na ya, o si fi binti ninu ijoba na fun omo Solomoni, nitori majemu ti o ba Dafidi baba re da **1 Awon oba 11: 5-13, 12: 16-20**. Ibaje-wipe oba Solomoni ko si awon isura re lo, iru-omo Solomoni ni ki ba ni ola ati oro julo ninu aiye loni. Ko eko lara asise oba Solomoni, mase si awon isura isura re lo.

**Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School**

**Ose Kokandinlogun: Osu karun Ojo keje, 2017**

**Akori oro: Nibo ni o to isura re jo si?** – Apa keji

**Eko Kika: Matteu 6: 19-24**

Ao tesiwaju ninu eko wa nigbati ao menuba awon isele ti yio sele si awon enia ti o gbe okan nwon le isura won ati awon enia ti nwon ko isura jo ni ona aimo.

**Mase gbekele oro aidaniloju**

O se pataki fun wa ni igba aiye wa ki a mase gbekele enikeni tabi ohunkohun bikose Olorun. Awon enia ti nwon ba gbekele Oluwa ni ao da abo bo, ti ao si da si i, besini ao se itoju nwon ni gbogbo akoko iwalaaye won. Nitorina, gbekele Olorun nikan.

**S'ogo ninu Oluwa:** Mase sogo ninu ola re tabi ki o gberaga ninu oro aidaniloju re. Enikeni ti o ba fe sogo, ni lati fi gbogbo ogo fun Oluwa Olorun. Nitorina, "Bayi li Oluwa wi: ki ologbon ki o mase sogo nitori ogbon re, beni ki alagbara ki o mase sogo nitori agbara re, ki oloro ki o mase sogo nitori oro re: Sugbon ki enikeni ti yio ba ma sogo, ki o se e ninu eyi pe; on ni oye , on si mo mi ; pe, Emi li Oluwa ti nse anu ati idajo ati ododo li aiye: nitori inu mi dun ninu ohun wonyi, li Oluwa wi" **Jeremiah 9: 23-24**. Fun idi eyi, ipokipo agbara ti o le wa lowolowo ati bi o ti wu ki ola ati oro re tobi to, sora, ki o mase so ninu okan re, tabi ni gbangba wipe "agbara mi ati ipa owo mi li o fun mi li oro yi" Sugbon ki o ranti Oluwa Olorun re; nitoripe on li o fun o li agbara lati li oro, ki on ki o le fi idi majemu re ti o bura fun awon baba re kale, bi o ti ri li oni yi **Deuteronomi 8: 17-18**. Mase gbekele isura re, sugbon gbekele Oluwa Olorun ti o fun o ni alafia ati ori-pipe lati ni oro ati agbara lati di olola gegebi majemu re.

**Gbigbe okan le isura yio mu o losi igbekun:** Ninu aiye loni, opo enia ni nwon gbekele awon isura won. Lotito ogoro enia ni nwon mbo awon isura won, ti nwon si nsin awon isura wonyi bi olorun. Awon enia ti won gbekele isura nwon ati ise owo nwon ni awon okunkun yio so di eru-isura. Esu yio si lo igbekele won ninu ohun asan aiye yi, lati fi nwon sinu ajaga ati lati di nwon ni igbekun. Bi iru awon enia wonyi ba kepe Oluwa ninu isoro won, Olorun ko ni gbo tiwon, nitori nwon ko gbekele e, beni nwon ko mo gegebi Olorun **Jeremiah 48: 7**. Fi igbekele re sinu Oluwa, mase fi igbekele re sinu isura re tabi sinu eleran ara. To isura re jo sinu ogba ajara Olorun, ki Olorun le bukun fun o, ki Olorun ma ba fi o gegun **Jeremiah 17: 5, 7**.

**Nwon yio subu:** Okankokan ti o fi isura re sinu ohun asan aiye wa ni ewu isubu; nitorina, o ko gbodo gbekele awon ohun ini re ninu aiye tabi ki o fi igbekele re sinu enia bikose sinu Olorun. Nigbati o ba fi igbekele re sinu Oluwa, ni Oluwa yio busi awon isura re, Oluwa yio si to o ni ona ti iwo yio rin; ki o ba le lo awon isura na lati se aseyori. A kowe re wipe, "Eniti o ba gbekele oro re yio subu: sugbon olododo yio ma gba bi eka igi" **Owe 11: 28**. Bibeli fi idi re mule wipe, awon ti nwon ni igbekele ninu ipa nwon, agbara nwon ati awon isura nwon, yio wole; beni nwon yio si subu. Sugbon awon ti nwon gbekele Oluwa yio dide duro sinsin **Orin Dafidi 20: 7-8**. Bi o ko ba fe subu, ni igbekele ninu Oluwa, ki o si ma to isura re jo sinu Ijoba re.

**Isura ko le se irapada emi re:** Eyiti o fi ye ki awon enia ni igbekele ninu Olorun ki nwon si ma to isura nwon jo sinu orun, opo awon enia ni igbekele ninu oro nwon, won si ngberaga ninu ola nwon. Iru awon enia yi kole ni idande fun ara nwon tabi gba awon ebi nwon sile lowo iku nipa sisan owo irapada fun Olorun. A ni lati mo wipe, kosi okunrin na ti o le san owo ti o to fun irapada tabi san isura ti o to lati gba awon ebi re sile lowo iku. Ko si enikan, bi o ti wu ki o se, ti o le ra arakunrin re, beni ko le san owo-irapada fun Olorun nitori re: Nitori irapada okan won iyebiye ni, isura ko to lati ra; o si dekun lailai **Orin**

**<u>Dafidi 49: 6-8.</u>** Niwon igbati irapada emi enia se iyebiye, ti kosi si owo ti o to lati ra, fi igbekele re sinu eje Jesu Kristi, eyiti a ta sile fun idande-ofe fun gbogbo eda-enia; nipa lilo isura re fun ise-Olorun ati tito isura jo sinu ijoba re ninu orun **<u>1 Peteru 1: 18-19, 1 Johannu 1: 7.</u>**

**<u>Nwon je olosi, are ati afoju:</u>** Enikeni ti o ba nleri ti o si nwipe "Emi li oro, emi si npo si i li oro, emi ko si se alaini ohunkohun; ti iwo ko si mo pe, osi ni iwo, ati are, ati talaka, ati afoju, ati eni-ihoho"

- Iru awon enia wonyi je olosi, nitori nwon ni ola ninu aiye, sugbon nwon ko ni ola ni odo Olorun nipa lilo isura won fun u.
- Nwon je are, nitoripe won ti sako kuro ni oju ona ododo.
- Nwon je talaka, nitoripe won ko to isura jo sinu orun, sugbon nwon nto isura won sinu aiye.
- Nwon je afoju, nitoripe Satani ti fi iboju bo won loju nipa ti emi.
- Nwon wa ni ihoho, nitoripe Esu ti ji aso-ogo won, o si ti gba aso-ogo kuro lowo won **<u>Ifihan 3: 17.</u>** Ni ifunra, mase fi ola re leri, tabi gbekele ola re, ni siso wipe "Emi li ola, mo ni ohun gbogbo ti okan mi nfe, kosi si ohun kan ti o ku ti mo nfe" bikosebe Satani yio lo ategun yi lati ja aso-ogo re gba.

**<u>Eyin oloro e sora:</u>** Awon oloro ninu aiye ko gbodo gberaga, nwon ko gbodo se emi-ni-mo-to-bayi tabi afojudi, beni nwon ko gbodo korira tabi fi oju-pa-enia-re. Nwon ko gbodo ni ireti ninu oro-aidaniloju won, bikose ninu Olorun, eniti npese ni kikun ati lai-sinmi fun idunnu won ati ohun gbogbo ti won nilo. Ojuse awa onigbagbo ni lati kilo fun awon ti o loro li aiye isisiyi, ati lati ko won, ki nwon mase gberaga, beni ki won mase gbekele oro aidaniloju bikose le Olorun alaaye, ti nfi ohun gbogbo fun wa lopolopo lati lo. Ki nwon ki o ma sore, ki nwon ki o ma po ni ise rere, ki nwon mura lati pin funni, ki nwon ki o ni emi ibakedun **<u>1 Timoteu 6: 17-18.</u>** Niwon igbati oro ko se gbekele, ni igbekele ninu Olorun, ki o si fi owo re sore; beni ki o ma po si ni ise rere nipa lilo oro re fun ise Olorun.

## Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

### <u>Isura aisoto</u>

Opo ninu awon oloro ninu aiye loni ni nwon ko oro won jo ni ona aisoto: awon oro ti enia ba kojo ni ona aisotito je irira si Oluwa. **Bi iru awon enia na ba fun ile Oluwa ni awon isura wonyi, tabi ti won lo awon isura na fun ise Oluwa, ko se itewogba, nitori oro aisotito ni.** Bibeli soro lori iru awon isele wonyi, wipe, Iwo ko gbodo mu owo oya agbere ati isura aisoto wa sinu ile Oluwa Olorun re fun ejekeje tabi fun idamewa. Iwo ko gbodo mu oro aisoto wa sinu ile Oluwa lati fi se irubo tabi dawo ninu ile Oluwa, nitoripe irira ni si Oluwa Olorun re **<u>Deuteronomi 23: 18.</u>** Lati isisiyi lo, siwo lati ma mu oro aisotito wa siwaju Olorun, niwon igbati isura jibiti ko se itewogba niwaju re.

### <u>Awon iyorisi isura aisoto</u>

Ao menuba awon iyorisi oro aisoto, lati le jeki awon enia mo ipalara, ti o wa ninu wiwa ola ni ona aimo; ki won si sera kuro ninu iwa ibaje yi.

**<u>Panpe iku ni oro aisoto:</u>** Orokoro ti enia ba fi eeru tabi etan kojo je panpe iku. Oro ti awon onijibiti ba kojo dabi kurukuru ti ki i pe, sugbon o je eroja fun iku. Nitorina, ini isura nipa ahon eke, o je emi ti a nti sihin ti sohun lowo awon ti nwa iku kiri **<u>Owe 21: 6.</u>** Niwon igbati ona eburu lati lola je ala asiwere, ti kosi yato si eniti o pokunso; e siwo kiko oro jo ni ona etan ati jibiti. E mase ko owo orile-ede nyin tabi owo ibi-ise nyin tabi owo ijo Olorun nyin je.

**<u>Oro eeru ko ni ere:</u>** Ohunkohun ti o ba jere nipa ise  ibi ko le ran o lowo rara, beni kosi ire kan ti o le jade lati inu oro ti a fi eeru kojo. Ola ti enia ba ni nipa sise aida, ko niye lori: beni oro ti a ba kojo nipa iwa-ibaje ko le gbe o be ibi ti o dara, tabi ki o fun o ni ayo ti ipe titi. A kowe re wipe, "isura iwa-buburu ko li ere: sugbon ododo ni igbani kuro lowo iku" **<u>Owe 10: 2.</u>** Niwon igbati oro-buburu ko niye lori, siwo

iwa ireje ati iwa jibiti.

**Oro aisododo ki i pe:** Awon enia ti nwon nko oro jo ni ona aisododo dabi aparo ti isaba lori eyin ti ko yin. Ni agedemeji aiye won oro na yio fi won sile tabi awon yio fi oro aisododo na sile nipa didagbere fun aiye. Ni opin iriajo won, nwon yio wa je asiwere. Bibeli wipe, " bi aparo ti isaba lori eyin ti ko yin, be gege ni eniti o ko oro jo, sugbon ki ise ni ododo, yio fi i sile lagedemeji ojo re, ati ni opin re yio jasi asiwere **Jeremiah 17:11.**

Idi pataki miran ti kofi ye ki awon enia o gba ona eburu lati ko oro jo ni itori emi-gigun. Awon ti nwon nko oro jo ni ona aisoto ma nku ni rewerewe nitori asise yi. Iwe mimo se apejuwe won wipe, "Nwon lo ojo won ninu oro; ni isejukan nwon a lo si ipo-oku" **Jobu 21: 13.** Bi o ko ba fe ku laitojo, tabi ki o lo igbesi aiye re ninu ogba-ewon, mase darapo mo awon asebaje, tabi awon alonilowo-gba, tabi awon apanilekun-jaiye. Mase se ogun-owo, tabi etutu-aje, tabi osole, bi o ba fe pe laiye lati gbadun oro re. Idi re niyi ti iku awon odo ati awon ewe se gbile ti o si gbode kankan ninu aiye loni: nitori gbogbo won kanju lati lowo nipa ona aimo.

**Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School**

**Ose Ogun: Osu Karun, 2017**

**Akori Oro: Nibo ni o to isura re jo si?** – Apa Keta

**Eko kika: Matteu 6: 19-24**

Eko yi ntesiwaju pelu awon ofin ti Oluwa Olorun so nipa awon isura re.

## Awon ofin Oluwa

Awa enia ko gbodo lo awon isura ti Olorun fifun wa lodi si Oluwa Olorun Eleda wa, sugbon a gbodo lo fun u ati fun ise re. Nitorina, mase lo isura re lati soko-ituka si ile elomiran, mase lo isura re lati da ija sile larin awon ore, tabi lo oro re lati fi da isote sile larin awon molebi re. Mase lo ola re gegebi ohun iwuri tabi ohun atilehin lati muki awon enia ma lepa ere-aisoto, eyiti o le muki nwon darapo pelu awon enia buburu.

**Je eniti o l'awo pelu oro re:** Mase je a-hun, sugbon je eniti o l'awo pelu oro re. Mase fi isura re se oju-rere si awon olola ati awon gbajumo enia nikan; sugbon lo isura re lati gbo ti awon talaka ati lati pese fun awon otosi. O ni asayan-oro ti a ma nso ni ile Yoruba wipe "Awon olowo nsore olowo, awon otosi na si nsore otosi elegbe won". Eyi je ohun ti gbile ninu aiye loni, sugbon ti Oluwa Olorun lodi si, idi re niyi ti Jesu Kristi fi gba iranse ti o pe si apeje ni imoran wipe "Nigbati iwo ba se ase osan tabi ase ale, ma pe awon ore re, tabi awon arakunrin re, tabi awon ibatan re, tabi awon aladugbo re oloro; ki nwon ki o mase pe o ewe lati san esan fun o. Sugbon nigbati iwo ba se ase, pe awon talaka, awon alabuku arun, awon amokun ati awon afoju: Iwo o si je alabukun fun; nitori nwon ko ni ohun ti nwon o fi san a fun o: sugbon ao san a fun o li ajinde awon oloto" **Luku 14: 12-14**. Bi o ba fe di eni ibukun, ti o si nfe ki a san esan fun o, ni ajinde

awon oloto, lo isura re lati fi gbo ti awon alaini enia. Je eniti nse iyo'nu si awon talaka ati awon otosi.

**Fi awon ohun-ini re se itore-anu:** Awon enia ma nse awawi, wipe idi ti awon ki ifi se itore-anu ni wipe; ki awon enia maba so ara won di atoro-je: sugbon ki awon na ba le fi owo nwon sise, ni alai-gbekele itore-anu tabi iranlowo esun-terete lati odo ijoba, ki nwon to gbo bukata ati je enia ninu aiye. Okan lara awon ona ti o daraju lati to isura jo sinu orun, ni ki enia o pin awon ohun-ini re fun awon talaka; ki o si lo oro re lati toju awon alaini. A kowe re wipe, "E ta ohun ti enyin ni, ki enyin ki o si tore anu; ki enyin ki o si pese apo fun ara nyin, ti ki igbo, isura li orun ti ki itan, nibiti ole ko le sunmo, ati ibiti kokoro ki iba a je" **Luku 12: 33**. Ofin Oluwa ni, nitorina, ta lara awon ohun-ini re tabi ki o ta gbogbo re; gegebi igbagbo re ba se tobi to, ki o si fi se itore-anu fun awon talaka.

**Isura die san:** O san ki enia gboran si ase Oluwa, nipa lilo awon isura re ni ona-tito, ki o si ni isura die; ju ki o ni agba-yanu ola, ki o si lo isura re ni ona ilodi. Nitorina, ki enia o ma gbe igbe-aiye ti o ni iberu Olorun san ju opolopo ola ti ohun ti akainiye isoro. Bibeli wipe "Die pelu iberu Oluwa, o san ju isura pupo ti on ti iyonu ninu re" **Owe 15: 16**. Ri daju pe, o lo oro ti Oluwa fi fun o ni ona ti o peye, atipe o lo oro yi fun ogo Olorun; ki o to ma bere fun oro-nla eyiti o le mu o sako kuro niwaju Oluwa.

**Pese fun ile Olorun:** Ojuse olukuluku eniti o fe lati to isura jo sinu orun, ni lati pese fun aini ile-Oluwa pelu gbogbo ipa ati agbara nwon. Eyi dara ju ki nwon ma pese fun awon ohun-irira, tabi pese fun awon eto-eranko, tabi pese fun awon ohun ti olorun da si ayika wa. Kristiani, e mase gbehin lati da'wo ni ibiti won ba ti nse ikowo-jo fun kiko ile-Oluwa; ki e si fi oyaya se abojuto aini awon enia-mimo re. Oba Dafidi nipa isipaya Emi mimo wipe "Pelu gbogbo ipa mi ni mo ti fi pese sile fun ile Olorun mi, mo ti pese opolopo wura, ati fadaka, ati

ide, ati irin, ati igi, ati okuta marbili, ati oniruru okuta iyebiye, ati oniruru awo. Pelupelu, nitori ni didun inu mi si ile Olorun mi, mo fi ohun-ini mi , eyini ni wura ati fadaka, fun ile Olorun mi, ju gbogbo eyi ti mo ti pese sile fun ile mimo na" **1 Kronika 29: 2-3**. Nje o npese fun Tempili Oluwa Olorun re, lati inu oro ti o fi fun o? Bi o ba nse eyi, se pelu oyaya ni tabi afipa-se? Se o nse eyi nitori okiki ni, tabi nitori karimi, tabi nitori igberaga ati ase-han? Mase ko oro re pamo, bikose ki o je mimo si Oluwa: o ko gbodo fi sura, beli o ko gbodo to jo; nitori ola re yio je lati fi toju awon ti ngbe iwaju Oluwa, lati je aje-yo onje ti yio te won lorun ati lati fi ra aso daradara fun nwon **Isaiah 23: 18**. Mase fi ere ise re pamo, sugbon lo lati pese ohun jije ati ohun mimu ati aso daradara fun awon eni-mimo ati awon iranse Oluwa; ti nwon ngbe iwaju re, ti nwon si nfi gbogbo agbara sise fun Oluwa.

**To awon isura re jo si orun:** Mase to isura jo fun ara re ni aiye, besini ki o dekun kiko isura jo nitori anfani tire nikan. Iwe mimo wipe, "E mase to isura jo fun ara nyin li aiye, nibiti kokoro ati ipara iba a je, ati nibiti awon ole irunle ti nwon si ijale" **Matteu 6: 19**. E to isura jo fun ara nyin li orun,  nibiti kokoro ati ipara ko le ba a je, ati nibiti awon ole ko le runle ki nwon si jale **Matteu 6: 20**. A ti so fun o na, ohun ti o daraju ti o le sele si enikeni, ni ki o to isura re sinu orun.

## Awon ileri Olorun

Olorun ni opolopo ileri fun awon enia ti o ba gboran si ase re, ti nwon si fi otito ba rin, nipa tito awon isura nwon jo sinu ijoba orun re. Ogoro awon oloro ni nwon ni okiki, ti okiki nwon si gbile kari aiye, awon wonyi je gbaju-gbaja jake-jado agbaiye, sugbon awon orun ko mo won; nitoripe nwon ko ni ibasepo ti o dan-moran pelu Olorun, besini nwon ko to isura won jo sinu orun.

**Iwo yio je awin-ni:** Lotito egbagbeje enia ni nwon je gbese ninu aiye loni, sugbon Oluwa yio si isura rere sile fun o, orun lati rojo si ile re li

akoko re, ati lati busi ise owo re gbogbo: iwo o si ma win orile-ede pupo, iwo ki yio si toro: bi o ba tele ase Olorun, ti o si to isura re jo sinu orun **Deuteronomi 28: 12**. Bi o ba fe ki Olorun si isura-rere re sile fun o, ki o si bukun ise owo re; o ni lati lo oro re daradara. Bi o ba fe di awin-ni, ti o ko fe ma win ohunkohun mo, to isura re sinu orun.

**Oro awon keferi yio je tire:** Awon onisowo agbaiye yio wa o wa, ti awon ti oro opo orile-ede ni won yio muwa fun o. Ohun alumoni inu okun ati oro oke-okun ni nwon yio ko wa fun o. Ola awon ile ti o jina yio je tire ati oro awon orile-ede yio to o wa. Iwe Isaiah wipe "Nigbana ni iwo o ri, oju re o si mole, okan re yio si yipada, yi si di nla: nitori ao yi oro okun pada si o, ipa awon keferi yio wa sodo re" **Isaiah 60: 5**. Bi o ba fe ki oro awon keferi je tire, lo awon isura re daradara.

Awon ase re yio si sile nigbagbogbo; a ki yio se won losan tabi loru, ki a le mu ola awon keferi wa sodo re, ki a ba si mu awon oba won wa **Isaiah 60: 11**.

**Isura okunkun ati oro ti a pamo:** Olorun yio fun o ni isura ti o farasin ni inu okunkun ati ola ti a fi pamo nibi ikoko. Iwe Isaiah wipe "Emi o si fi isura okunkun fun o, ati oro ti a pamo nibi ikoko, ki iwo le mo pe, emi Oluwa, ti o pe o li oruko re, li Olorun Israeli" **Isaiah 45: 3**. Bi o ba fe ki Olorun jeri iwa-laaye re ninu aiye re, je eleti-omo, ki o si fi ogbon lo isura re. Fun idi eyi, a kowe re wipe, isura nla ati isura aidiyele nbe ni ile awon olododo, sugbon ninu owo enia buburu ni iyonu. Eyi tumo si wipe, awon enia rere yio ni oro, sugbon awon enia-ibi yio padanu oro ti won ni **Owe 15: 6**. Bi o ba nfe ki ola-nla joko pe titi ninu ile re, mase si isura re lo.

**Iwo yio sogo ninu ola:** Ao pe o ni Alufa Oluwa: nwon o ma pe o ni Iranse Olorun wa: iwo yio je oro awon keferi, ati ninu ogo won li iwo yio ma sogo **Isaiah 61: 6**. Fun ileri yi lati wasi imuse ninu aiye re, o ni lati lo isura re ni ona ododo. Siwaju-si, ola ati oro yio wa ni ile re, ola-

ailopin yio ma gbe ninu ile re, ododo ati ise rere re, yio duro lailai **Orin Dafidi 112: 3**. Fun o lati li ola, ki o si se aseyori, o ni lati lo isura re fun Oluwa. Fun ile re lati kun fun ola ati oro, o ni lati to isura re jo sinu orun.

**Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School**

**Ose Kokanlelogun: Osu Karun Ojo Kokanlelogun, 2017**

**Akori oro: Nibo ni o to isura re jo si?** –Apa Kerin

**Eko kika: Matteu 6: 19-24**

Eko yi ntesiwaju pelu awon apejuwe ati awon iyorisi ti a ko sinu Bibeli, lati fi imo fun awon enia ati ki nwon le ni oye akori-oro yi daradara.

## **Awon apejuwe**

Awon ohun ti ao ka, ni igbeyewo awon oniruru apejuwe ti yio ran enia lowo lati se ipinnu rere, lori bi enia yio ti se lo isura re ati ibiti enia le to isura re jo si.

**Sora fun itanje ola:** Kiyesara, ki oro-Olorun ti o ti gbo, le so eso, ki won si so ogororun ninu aiye re; gegebi awon irugbin ti o bo sori ile olora. Ri daju pe oye akori-oro yi ye o daradara, ki o si lo awon oye na ninu gbogbo akitiyan ise-oojo re ati irinajo re.

Mase gba Satani laye lati je o lere, nipa lilo aniyan-aiye ati adun-aiye pelu itanje ola ati oro lati fun oro ti o ti gbo pa; ki o si so o di alaileso, gegebi irugbin ti o bo sarin egun ninu Bibeli **Matteu 13: 22-23.** Nisiyi, niwon igbati o ti mo okan lara awon ona ti Esu ngba lati sise, mase fun ni aye lati lo arekereke awon isura re lati fun oro ti o ti gbo pa: sugbon di igbagbo re mi sinsin. Mase je alaileso, sugbon je irugbin-eleso ki o ba le dojuti Satani.

**Mase si iwa wu:** Oba Hesekiah je oloro, Bibeli wipe Hesekiah si li oro li opolopo ati ola: o si se ibi-isura fun ara re fun fadaka, ati fun wura, ati fun okuta iyebiye, turari ati apata, ati fun oniruru ohun-elo iyebiye. O ni ile-isura fun ibisi oka, ati waini, ati ororo, ati ile fun

oniruru eran ati agbo-eran; nitoriti Olorun fun u li oro li opolopo **2 Kronika 32: 27-29**. Oba Hesekiah se asise, lehin igbati Olorun wo arun re san, okan re gbega; beni ko si tun pada san gegebi ore ti Olorun se fun u. O kuna lati fi emi-imore han nipa didupe lowo Oluwa Olorun fun ohun gbogbo ti o se fun u **2 Kronika 32: 25**. Oba Hesekiah tun se afihan gbogbo isura re fun awon emewa ti oba Babeli ran wa. Eyiti iba fi ronupiwada, ki o si re ara re sile nigbati woli Isaiah mbere wipe "kili awon okunrin wonyi wi ati nibo ni nwon ti wa si odo re? Nigbana ni Isaiah wipe, ojo mbo, ti ao ko gbogbo nkan ti mbe ninu ile re ati awon enia re lo si Babeli. Oba Hesekiah fi igberaga dahun wipe "ko ha dara bi alafia ati otito ba wa lojo mi?" **2 Awon oba 20: 14-19**. Ko eko lara asise oba Hesekiah, re ara re sile, mase fi ola tabi oro re gberaga, beni ki o mase fi mu ogbe-okan wa fun awon elomiran.

**Ikoro nduro de awon ti won si isura nwon lo:** Itan okunrin oloro ati Lasaru je apejuwe ti o dara ninu Bibeli. Lasaru je alagbe ti o ma nsa onje je labe tabili okunrin oloro yi. Awon mejeji ku u, awon angeli gbe Lasaru lo si okan-aiya Abrahamu, nigbati okunrin oloro yi losi orun-apadi nibiti o ti nje irora. Okunrin oloro yi bebe wipe ki Lasaru ke ika bo omi, ki o fi si on ni ahon lati pa oro-ina. O tun bebe wipe ki a ran enia kan losi inu aiye lati kilo fun awon arakunrin on; ki awon na maba pari irinajo won si orun-apadi. A ko se awon ebe re mejeji fun, beni o njoro ninu ina ni orun-apadi **Luku 16: 19-31**. Bi o ko ba fe pari irinajo re si orun-apadi, lo isura re lati fi bojuto awon talaka ati awon alaini. Bi o ba fe wo ile-ologo, lo oro re fun Oluwa.

**Ni oro lodo Olorun:** Awon oloro le ba ijakule pade, nitori opolopo nwon ni a ki yio fi aye gba lati gbadun ola won. Ile okunrin oloro kan so eso opolopo. Osi ro ninu ara re, wipe, Emi o ti se, nitoriti emi ko ni ibiti emi o gbe ko eso mi jo si? O si wipe, "Eyi ni emi o se: emi o wo aka mi pale, emi o si ko eyiti o tobi; nibe li emi o gbe to gbogbo eso ati oro mi jo si". Emi o si wi fun okan mi pe, "Okan, iwo li oro pipo ti a to jo fun opo odun; simi ma je, ma mu, ma yo". Sugbon Olorun wi fun u

pe," iwo asiwere, li oru yi , li ao bere emi re lowo re: nje titani nkan wonyi yio ha se, ti iwo ti pese sile?" Bayi ni yio ri, fun gbogbo eniti o to isura jo fun ara nwon, sugbon ti won ko li oro lodo Olorun **Luku 12: 16-21**. Ni oro lodo Olorun, nipa tito isura jo sinu ijoba re, ki o ba le ni anfani lati je ninu laala re, ki o si gbadun ola re.

**Bojuto awon talaka ati alaini:** Jesu gba ijoye kan ti o bere lowo re wipe "kili emi o se ti emi o fi jogun iye ainipekun?" ni imoran wipe, pa awon ofin Olorun mo. Nigbana ni ijoye yi wipe, "gbogbo nkan wonyi li emi ti pamo lati igba ewe mi wa". Jesu wipe "ohun kan li o ku fun o sibe: lo ta ohun gbogbo ti o ni, ki o si pin fun awon talaka, iwo o si ni isura li orun: si wa, ki o ma to mi lehin." Nigbati o si gbo eyi, inu re baje gidigidi: nitoriti o li oro pipo **Luku 18: 18-23**. Mase banuje, sugbon tujuka, nitori Jesu Kristi Oluwa ti so ohun ti iwo yio se lati jogun ijoba orun. Lotito, o le soro fun awon enia ti o ni oro-nla lati ta ohun gbogbo ti nwon ni; sugbon ti igbagbo nwon ba kere, nwon le ta ohunkohun ti o ba rorun fun nwon lati ta, ki nwon si pin fun awon talaka.

**Sa ipa re:** Olukuluku ni lati sa ipa nwon, ni lilo isura ti Olorun fifun nwon, ki nwon si se iwon ti won le se. Botiwu ki oro re kere to, jowo mase so wipe ola re ti kereju: atipe ohunkohun ti o ba dasi ise-oluwa, koni ni itumo tabi ko je nkankan. Ko eko lara obinrin opo inu Bibeli ti o so owo ide wewe meji sinu apoti-isura ile Oluwa. Jesu Kristi wipe, talaka opo yi so sinu apoti isura ni ojo yi, ju gbogbo awon ti o so sinu re lo. Idi re ni pe "gbogbo enia nso sinu apoti isura ninu opolopo ini won; sugbon obinrin opo yi ninu aini re o so ohun gbogbo ti o ni si i, ani gbogbo ini re **Marku 12: 41-44**. Niwon igbati o je wipe owo ti o ba da ninu ile Oluwa tabi ohun ti o ba pin fun awon talaka ni lati je gegebi iwon ibukun tabi ola ti Oluwa fifun o; nitorina mase kuna lati dasi ise Olorun gegebi oro ti o fi fun o.

## Awon iyorisi

Opolopo awon iyorisi ni a menuba ninu Bibeli, sugbon mase banuje lati lo awon isura re fun ise Oluwa Olorun re; nitoripe Olorun fe oninudidun olore. "Olukuluku enia ki o se gege bi o ti pinnu li okan re; ki ise afekunse, tabi li aigbodo mase: nitori Olorun fe oninudidun olore" **2 Korinti 9: 7.** Ranti oro ti jesu so ti o mu okunrin ijoye ni banuje "Mo si wi fun nyin ewe, o rorun fun ibakasie lati wo oju abere, ju fun oloro lati wo ijoba Olorun lo" **Matteu 19: 23-24.** Lotito, a nilo oro lati wa laaye ati lati gbe nile aiye, beni, bi enia ba ni ola ki ise ese, niwon igbati o ba ti nlo oro re gegbi ase Oluwa; nipa tito isura re jo sinu orun: igbana ni iwo le jogun ijoba orun.

**Dekun wiwa ola gbigbona:** Opolopo enia ninu aiye loni, ni nwon wa ni opopo-marose nipa ati lowo; awon wonyi si nkanju lati di oloro. Iru awon enia na, ni lati mo pe ewu-nla ro mo iru iwa yi. Nwon ni lati mo wipe "ifarabale ati iforiti ni nmu enia gbe igba-oroke ninu idije." Ogoro enia ni nwon ise ahun, nitori ati tete ni ola, ni alaimo pe, ofo yio se nwon. Awon wobia enia nsare si ola, sugbon nwon ko mo pe ewu yio bori won. A kowe re wipe "Eniti o kanju ati la, o li oju ilara, ko si ro pe osi nbowa ta on" **Owe 28: 22.** Mase je onimo tara-eni-nikan tabi je eniti nkanju lati ni ola, ki igbehin re maba buru jai.

**Mase alai-nani awon talaka:** Awon enia oniwa afemi-afemi, ti nwon ko lo isura nwon lati toju awon talaka, yio ni idojuko pipo. Awon oloro ti nwon se alai-nani awon talaka, ni lati mo wipe iwa imotara-eni yio so nwon di akuse tabi talaka nikehin. Enikeni ti o nni talaka lara, lati ko ola jo fun ara re; ti o si nfi opo ebun fun awon olola egbe re; yio di akuse ni ikehin aiye re bi ko ba kiyesara. Bibeli wipe, "Eniti o nni talaka lara lati mu oro re po si, ti o si nta oloro lore, yio di alaini bi o ti wu ki o se" **Owe 22: 16.** Mase yan talaka je nitori ere, sugbon fi awon isura se itoju nwon daradara.

**Ao fi isura re fun ije:** Awon ota yio fi iwa-ipa ati aisoto gba oro re. Olorun yio fi ohun gbogbo ti o ni fun awon olodi tabi awon abinuku

re, nitori awon ese re. "Ohun-ini ati isura re li Oluwa o fi fun ije, li aigbowo, nitori gbogbo ese re ni agbegbe re" **Jeremiah 15: 13.** Sa fun aisedede, ki o si lo isura re fun Oluwa, ki a ma ba fi oro ati ohun-ini re se ije.

**Oro ti a fi iwa-asan kojo yio jooro:** Oro ti a fi iwa-asan kojo yio dinku, beni owo eeru yio poora ni kiakia. Oro ti enia ba kojo lati inu iwa owo-gbigbona yio jooro, beni ola ti enia fi jibiti kojo yio poora laitojo. A kowe re wipe "Oro ti a fi iwa-asan ni, yio fasehin; sugbon eniti o fi ise-owo kojo ni yio ma po si i" **Owe 13:11.** Ranti wipe ohun ti a ko ba jiya fun ki to'jo, ohun ti a ba sise fun ni ipe lowo eni. Nitorina, mase wa isura aisoto.

**Oro awon elese ni ao fi tore:** Oro awon elese ni a tojo fun awon olotito, gbogbo oro ti awon elese ba ni, a kojo fun awon olododo ni. "Enia rere fi ogun sile fun awon omo ati iru-omo re; sugbon oro elese li a to jo fun olododo" **Owe 13:22.** Niwon igbati o je wipe oro ti a fi iwa-asan kojo yio je ti awon olododo, ti ao si fi isura awon elese fun awon olotito; sa fun ese ki a ma ba fi oro re fun awon olododo. Je eni iduro-sinsin ki a ma ba fi oro ti o se laala fun ati awon ti o toju ni ibi ikoko, tore fun awon eni-bi-Olorun.

Lakotan, ranti wipe ibukun Oluwa ni imu ni ila, ki isi ifi laala tabi ogbe-okan pelu re. Nitorina, lo isura re fun Oluwa, ki o masi se wa oro aisoto **Owe 10:22.**

**Edidi: Luku 12:34:** Nitori nibiti isura enia gbe wa, nibe li okan re yio gbe wa pelu.